26 NOV 1965



# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO IAWA

No 1,'64 SATURDAY NOVEMBER 20, 1965 (2D)


## Awon Akeko Egbe Afenifere kowe Si Ademola

IBADAN:- Ni ojo ojo Bo ti ise ojo kejidinlogun osu yi ni awon Igbimo Akeko ti egbe Afenifere ti ile eko giga julo ti Unifasiti Ibadan ni awon omo egbe na ti ko iwe si Adajo agba fun apapo ile Naijiria Oloye Adetokunbo Ademola lori Igbimo awon omo ile Yoruba ti a npe ni "Commiltee of Yoru ba Elders" ti awon Igbimo na si se ikede pe awon yio pari edeaiyede to be sil o ni Ipinle Iwo Orun Naijiria bayi.

Ninu iwe ti o jade lati owo Akowe egbe Akeko ti ile eko giga julo Unifa-siti ilu Ibadan ni Ogbeni Nimbo Fani Kauimi ti se alaye ninu iwe ti nwon ko si Oloye Adetokunbo Ademola pe awon gbo pe on ni Alaga Igbimo awon omo Ile Yoruba ti nwon fe pari edeai-yede to nsele ni Ipinle Iwo Orun Naiji-ria lori abayori idibo si Ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinle Iwo Orhn Naijiria

Awon Akeko egbe Afenifere ninu ile eko giga julo ti ilu Ibadan ni nwon ti tun se alaye pe ti Igbimo ti Oloye Ade-mola ise Alaga re ti o fe pari edeaiyede na pe itan ni yio so ara re bi awon Igbimo na ba le se eto lati pari ija na.

WO OJU EWE KEFA

## OMO EGBE DEMO SO PE :

# AWON NFE AWOLOWO NI OLORI ILE NAIJIRIA !

EKO:- N nu oro kan to jade lati enu okan ninu awon omo egbe Demo ti Ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria Ogbeni G, I, Akinyele ni o ti se alaye pe awon nfe Olori egbe Afenifere Oloye Obafemi Awolowo to wa l'ogba ewon bayi lati wa gegebi Olori ile Naijiria.

Ogbeni Akinyele so ey ti ilu Eko ni ojo ojo'Bo ti se kejidinlogun osu yi lati je ki nwon pari ija to wa larin egbe Afenifere ati egbe De-mo ati pe ki awon egbe me-jeji na jijo papo ki nwon si le da Oloye Awolowo sile l'ogba ewon ati awon omo lehin re,

Ogbeni Akinyele tun se alaye pe ki nwon tete kesi Alakoso apapo Ijoba Naiji-ria ati apapo Ijoba ile Nai-jiria lati le dariji awon enia to salo si ile Ghana lati lo da abo bo ara won ati pe ki nwon si tete fi orin si iru ohun ti o je wipe o le pa orile ede Yoruba run,

Ogbeni Akinyele nfun Oloye Adeniran Ogunsanya ni esi oro ti o so ni ojo Aje ti ise ojo ked gun osu yi eyi-ti Ogbeni Akinyele tun se alaye pe ko si igbati nwon ba fe pari edeaiyede to wa lari egbe Afenifere ati egbe Demo eyiti o je wipe egbe Alakuko ko fe ma gba be,

Ogbeni Akinyele tun se alaye pe ko si igbati nwon ba fe ki eto ise kan wa fun orile ede Yoruba eyiti o je wipe egbe Alakuko lo fe ma baje ati pe kini o le fia iru nkan bayi wa ti egbe Alakuko le fi mahu iwa iru bayi?

Ogbeni Akinyele tun se alaye pe ti awon egbe ose-lu mejeji ba le papo eyiti se egbe Afenifere ati egbe Demo o ni eto alafia ati ijo ba rere yio le fokanbale si Ipinle Iwo Orun ati pe yio si tun mu ki orisirisi ise ma de si Ipinle na

Ogbeni G I Akinyele tun se alaye pe egbe Alakuko nfe ki Ipinle Iwo Orun jo-na nitori pe nwon si ti mo pe ti Ipinle Iwo Orun Naiji ria ba le wa lori eto ofin re re ti ifokanbale ati alafia ba si padabo si Ipinle na o ni egbe Alakuko ko le se eto akoso Ijoba Ipinle na lai lai ati pe nitori na ni egbe Ala-kuko si nfe ki Ipinle na ma le toro.

Omo egbe Demo na tun se alaye pe Oloye Adeniran Ogun ko so otito kankan nigbati o mo wipe egbe Ala kuko si fi a a ko rogbodi-yan to sele ni Ipinle Iwo Orun Naijiria nigbati egbe Alakuko si ba egbe Olomo-kulumbu (U P P) gbimopo lati jijo se eto akoso Ijoba Ipinle na lasiko na,

Ogbeni Akinyele tun se alaye pe on Ie ki Oloye Adeniran Ogunsanya lo se iranti pe awon minista egbe Alakuko lo so fun Alakoso apapo Ijoba Nai-jiria lati se eto ofin pajawi-ri si Ipinle Iwo Orun Nai-jiria lasiko ti edeaiyede be sile larin awon omo egbe Afenifere.

O tun se alaye pe ni asiko ti edeaiyede be sile larin awon omo egbe Afenifere eyiti nwon fi se eto ofin pajawiri si Ipinle Iwo Orun Naijiria o ni egbe Alakuko lo tun gbe eto bi nwon yio ti se iwadi si awon Ile Ise Ijoba Ipinle

WO OJU EWE KEFA

## Awon Olopa Yinbon Pa Onimoto Kan !

MUSHIN:- Gbogbo ilu gbojikan fun ariwo nigbati awon olopa da onimoto kan Raimi Adigun eni odun mejidogbon duro nigbati o nwa moto re bo lati adugbo kan ti nwon npe ni Isolo ti awon olopa na ni ki o duro sugbon nigbati ko duro ni olopa kan ba yinbon fun un, ti o si pa Direba na ku banuba nu ni katukutu owuro ana ojo Eti ti ise ojo kokandinlogun osu yi.

Eniti oro na soju re se alaye fun oniwe Irohin wa ni Mushin pe nigbati onimoto na sise tan ni ale ijeta o gbe moto boosi re nomba L H 7386 lo si ile onimoto na sugbon nigbati i'le ojo keji mo, ni o ba gbe moto na.

Bi o si ti fere de oja Mushin nibti o gbe fe lo ko ero ki o ma lo si Agege ni olopa ba da a duro nigbati yio fi duro, olopa ti yinbo fun lati ehin o si pa awamoto na.

A gbo pelu wipe nigbati olopa na yinbon pa onimoto na. okun-rin na ku lojukanna, sugbon mo-to na ko le duro, eniti o wa ni egbe re ni o tete yi owo moto na si oju ona ti ko jeki moto na se awon enia ti nwon wa ni egbe ona lese.

Awon Olopa ti gbe oku eni a moto na lo si Ile Iwosan Ikeja fun ayewo awon Dokita. Irohin awon Olopa fi ye wa pe, eniako gbodo jade lehin agogo meje ale ni Mushin titi di agogo meje owu-ro ojo keji

Ni owuro yi ti ise ogunjo osu yi ni ofin isede ti Ijoba se yio dopin. Bi nwon ba si tun fi kun ojo ti nwon yio mu ofin na kuro o tun ma a gbo o.



Kaasa, igi da ! Aworan oke yi ni ti moto Raimi Adigun nomba LH 7386 ti awon olopa Mushin yinbon pa Lehinti nwon y inbo na tan ni onirohin wa to ya aworan oke yi.

# SURU LERE (APA KINI)

Mo ki nyin o, Ẹnyin enia Adakẹdajọ baba mi ko ni jẹki ọwọ tẹ nyin o mo ki Olotu iwe Irohin Imọlẹ pe ẹ kuọjọ mẹta, ẹ ku aigbagbe ohun rere ko ni tan ni ile nyin o ọmọ ti a sọ fun pe iyan nbọ ti oni onjẹ toku nilẹ ko le to wa jẹ mọ nitorina ẹ jẹki ta a baba wa lẹnu ki onjẹ ile ta le to wa je sibẹsibẹ iyan npọ si.

O da mi loju pe awọn na si nlọ si oko Ẹmi, enyin enia e ṣebi Joseph; kini Joseph ṣe? Nigbati Adakedajo gbe Josefu dide lati ṣe olugbala awọn ẹgbọn re ti iṣe awọn ọmọ ile Israeli. Nigbana ni Josefu la ala; o si rọ ala na fun idile Isreali awọn ẹgbọn-Josefu ti nwọn mọ itumọ ala si binu lakotan nwọn ta olugbala si oko eru nitori ki nwọn maṣe le fi ori balẹ fun un

A mu Josefu sokale wa si Egipti Ijoye Farao kan ran Oluwa si wa pelu Josefu o si ṣe alasiki enia Josefu si ri oju rere lọdọ Oluwa Re on si nsin a si fi je

## Lati Ọwọ Ọmọ - Oba Adakẹdajọ

olori ile Oluwa rẹ ati ohun gbogbo ti o ni o si ṣe lati igba ti o ti fi ohun gbogbo ti o ni o si ṣe lati igba ti o ti fi Josefu jẹ Olori ile rẹ ati Olori ohun gbogbo ti o ni.

Adakẹdajọ si ile ara Ekipti na nitori Josefu o si ṣe lẹhin nkan wọnyi ni aya Oluwa rẹ gbe oju le Josefu o si wipe BAMIṢE!

Ṣugbon on kọ lati bi e ohun kankan po Ah! enyin enia baba mi iwa otito ti nfi iya jeni ni ona to jin ni Adakedajo ko ni si lati gba awọn enia tire lowo iya ti ko to

### AKOBA NKO?

O ṣe ni akoko yi ti Josefu wọle bo lati ṣe iṣẹ re ti ko si ọkunrin ninu ile aya oluware si dimu ti a sọ pe, Ba mi ṣe o si jowo aṣọ re si lowo o bo si ode nigbana ni e ke pe awon obinrin ile re Ẹ wo o o wole to mi wa lati ba mi ṣe obinrin na si wi fun oko re pe Ẹru Heberu ti iwo mu wa sihin o, wọle to mi lati fi mi ṣe eleya Oluwa Joefu binu, ṣugbon Oluwa wa pelu Josefu nigbati a fi sinu Tubu·

### OMI PUPỌ KO LE PA INA IFẸ

Joṣefu tun ṣe lori Tubu sibẹsibẹ o ni tubu si fi gbogbo awọn ara tubu le Josefu lọwọ ọna ti a nrin lati rsubu to ba ya Adekẹdajọ a tun gbe ni dide Josefu ko si wọ ọrọ nipa ala o tun lọ tunmọ ala ninu Tubu Afini muna ko ni gba ẹmi ifarada lọwọ o,

Ẹniti ṣe alaiṣotitọ ki o ma ṣe ṣo Ẹniti ṣe Ẹlẹgan ki o ma ṣe niṣọ, Ẹniti nṣe olododo ki o ma ṣe niṣo ẹni ti iṣe mimọ ki o ma ṣe niṣo ṣiyesi ẹmi nbọ kankan ere si nbẹ pẹlu lati san fun olu kuluku gẹgẹbi iṣe wọn. O san fun Josẹfu nigbati orọ itunmọ ala fun Ọba Farao

Josẹfu ni oṣe balẹ ile na oni o nta onjẹ fun awọn ara kunrin Josẹfu si wa a wọn si tẹ ORI NWỌN BA FUN NWỌM DOJUBO LẸ, on si ni awon ara kunrin rẹ osi mọ won su gbon ofi ara rẹ ṣe aycyi fun won osi sọrọ ako si won

Josẹfu si ranti ala won ni ti a si wọn o si wi am ni ẹyin? Cwon si wipe Beko Oluwa" ni sugbon lati ra onjẹ ni awon iransẹ rẹ ṣe wa " Ana iranṣẹ re ki ami " Bi aiye on orun nkoja lo kinikini ninu oro Adkẹdajo ki yio lo ni ala iṣe.

Nigbati Josẹfu si bo wa le nwon mu ore ti owa ni owo won fun wa sinu ile nwọn si TẸRIBA fun ni ilẹ ara Baba wa iranṣẹ le

### EYI TO RONU

Ni ipari apa kini ẹ jẹki afi isẹlẹ to se fun nyin lọgbọn si ọrọ yi

Bi mo ti joko lori adata nitori orun ti bere si ran gẹgẹbi iṣe lile ti afi fun osupa ti ṣe iṣẹ tere dari gẹgẹbi ẹniti ko yẹ ki oṣe eje iṣẹ osan labẹ igi ọpọ tọ ni mo j ko nitori iṣẹ lile ti orun nṣe ti ara mi ko gba ṣugbon iranṣẹ ni mi iranṣẹ toru iranṣẹ kan ko gbobọ e i iranse ẹlẹgbẹ rẹ lowẹ. Bi mo ti nronu nipa ti orun ti o yara nṣe iṣẹ tirẹ nitori akoko diẹ ni ohunkohun ni lati lo lo rir ile ibaṣe eranko tabi ọkan ti a nb nsun nie tabi enia ti o binu wnọ

WO OJU EWE KARUN

# Ajọyọ Ajọdun Kejidinladọta

Irohin ko to afojuba ni are aladun ti awọn ọmọ ogun ṣọja ati awọn ọlọpa ṣe ni ọjọ Aikun ti iṣe ọjọ keji osu yi nigati awọn ẹnia orilẹ ede ilẹ Roṣia nṣe iranti ajọyọ ajọdun ọdun kejidinla dọta ti awọn enia orilẹ ede na gba Ominira



Aworan ti ẹ nwo loke yi ni ti awọn ṣọja ti nwọn nṣere kekiri gbogbo ode ni ọjọ na ni adugbo kan ti awọn npe ni "RED SQUARE" ni olu ilu Rosia ti nwọn npe ni Mosco ọjọ na

Irohin fi ye wa wipe yika gbogbo enia agbaiye ni awon enia orilẹ ede ile Rosia ṣe ayẹyẹ ajọdun na ni ọjọ na na paapajulọ ni gbogbo orilẹ ede ti Ijọba Rosia gbe tini awọn Asoju Ijọba

Aworan ti ẹ nwo loke iwe yi ni ti awọn ṣọja ti nwọn yika gbogbo iju ni ọjọ na.

## Iwe si Olotu Irohin Imole

OLOTU IMOLE

### Ṣoja Ko Le Pari Rogbodiyan Iwo Orun

Olotu. Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye diẹ ninu iwe nyin lo kun fun ọgbọn ati ovc lati kesi alakoso apapọ Ijọba Naijiria Alhaji Abubakar Tafawa Balewa lori ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lori ibo eru ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ sọ pe awọn lo wọle.

Mo fẹ ki Alhaji Abubakar lọ mọ daju pe ṣọja ati ọlọpa ko le ṣe iṣẹ ohun o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwo Ọrun bikoṣe pe ki nwọn tete pọ awọn ẹgbẹ oṣelu mejeji eyiti iṣe UPGA ati Dẹmọ ki nwọn si ṣe eto idibo miran eyiti awọn yio yan awọn Igbimọ eto ibo miran yatọ si ti eyiti o kọja.

Inu ana enia Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn ti jo ile rẹ ni ina ati awọn ọgọrọ eda to ti padanu emi wọn lori rogbodiyan to nṣẹle ni Ipinlẹ na yio ti nwọn ba le ọyi.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ fun nyin o.

Emi ni
Ọmọ Alarẹ
Ijẹbu Imushin

### Adegbenro Ni Awa Nfẹ

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin akọmọlede lati fi ye awọn elori ile Naijiri ati paapa julọ Alhaji Abubakar Tafawa Balewa lori eto idibo ti awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria di ni ọjọ kọkanla oṣu to kọja ati pe Alhaji D S Adegbenro ni awa nfẹ gẹgẹ bi Alakoso Ijọba Ipinlẹ na nitoripe ẹgbẹ rẹ lo wọle idibo to kọja lo yi

Awa enia Ipinlẹ Iwọ Orun ti mọ ohun ti oju wa ri fun ọdun mẹta ti ẹgbẹ Dẹmọ fi ṣe eto akoso Ijọba ati pe a ko tun gba a adura pe ẹgbẹ Dẹmọ ni yio tun ṣe eto akoso Ijọba Ipinlẹ na eekeji.

Akoso Ijọba ti oloye Samuẹl Ladoke Akintọla ṣe ti su wa a ko fẹ Ijọba rẹ mọ bikoṣe wipe Alhaji Adegbenro ni awa nfẹ ninu eto akoso Ijọba Ipinlẹ na, Owo koko ti odi olubantẹ ti to wa ṣe arekọgbọn nitori eyi awa nfẹ Adegbenro gẹgẹbi

Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Emi ni
G.Ade Awonaike
IBADAN

### Ofin Pajawiri Lo To Ni Iwo Orun

Olotu jọwọ gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe rẹ to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Alakoso apapọ Ijọba Naijiria ati Adele Olori ilẹ Naijiria lati rete lo ipa wọn rere ki nwọn yara ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ Iwọ Orun lori rogbodiyan idana sanṣe ati ọkẹ ainiye emi to ti ṣofo ni Ipinlẹ na lori idibo to kọja yi.

Eleyi yio si dara bi awọn Olori ilẹ wa mejeji yi ba le tete ṣe ofin pajawiri si Ipinlẹ na ki nwọn yan awọn Ṣọja ati Ọlọpa lati ṣe ṣe eto akoso Ijọba Ipinlẹ na.

Ninu ọdun 1962 ni apapọ Ijọba ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ Iwo Orun eyiti o jẹ pe ohunti o ṣẹlẹ ni Ipinlẹ na ko to ohunti o ṣẹlẹ ni Ipinlẹ na bayi pe eleyi si ṣe amojuto Ijọba lati mu oju to ohunti o nṣẹlẹ.

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mu ọko Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
Adesina Adeṣanya
EKO

### Awa Ko Fẹ Ijọba Jibiti

Olotu, Dakun gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ to nta bi akara gbigbona lati fi ye awọn Olori ilẹ Naijiria ati paapa julọ awọn ẹgbẹ ti nwọn nsọ pe awọfi lo wọle idibo to kọja eyiti iṣe ẹgbẹ Dẹmọ awa enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ko fẹ ki awọn ẹgbẹ Oṣelu ti iṣe ẹgbẹ jibiti ati ọdalẹ ṣe eto akoso Ijọba wa eyiti o jẹ wipe a ti sun wa lori eto akoso ẹgbẹ Ọlọwọ ti ṣe kọja.

Lati nkan bi ọdun mẹta ti ẹgẹ olowo ti fi ona ẹru gba akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria ni gbogbo bi awọn ẹgbẹ naa ti nṣe eto Ijọba ko ti tẹ wa lorun ti o jẹ pe pẹlu agbara ni awa ologbe ipinlẹ Iwọ orun fi njẹnn.

Inu awa enia ipinlẹ yi yio eton b. Alakoso apapọ Ijọba ba le tete lo ipo rẹ rere ki awọn to ke igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ iwọ orun Naijiria ka ki nwọn ṣe idibo titun.

Emi ni,
Joke Hassan,
IJẸBU-ODE

# O Ti De Jaburata

Eyi n i lati kede fun awọn Onibara wa pe. Iwe Itumo Ala. I ṣẹ Wiwo, ọjọ ibi ọmọ de lati Oogun Ajẹbidan alapapo wa nile fun titi nisisiyi, tete wa ra irẹ loni ki o to tan

A s i tun ṣeṣẹ ṣe Iwe Itumo Ala miran ati owo Joseph Alala 9

Irohin ko to afojuna 3/6d pere ni, eyọ kan, mejila tabi dosin ni rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9, Iyala Street,
Mushin.


Ọgbẹni J. O. Shoyinka

A s i nfẹ awọn ti yio ma ba wa ta awọn iwe wa na

Tete wa si ọdọ Olotu

POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin

The NEW HOOVER
Washing Machine
Makes Clothes
Whiter and Brighter
It's easier the....
HOOVER way



The NEW HOOVEMATIC washes ... rinses spins dry 5lbs. of clothes in 4 minutes all in one continuous operation. That's the amazing performance of the new Hoovermatic, a combined Washing Machine and Spin Dryer.

AVAILABLE AT
LEVENTIS TECHNICAL
MARINA — IDDO — IBADAN —
KADUNA — JOS — KANO —
P. HARCOURT — ABA.
and Kingsway Stores.

# OLOLA ATOHENGBE PADADE LATI ILU OYINBO

Ni ojo ojo 'Ru ti ise ojo kẹtadinlogun osu yi ni Ọlọla H. F. E. Atohengbe ọkan ninu awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pade lati ilu Oyinbo Czchoslovakia fun ibẹwo ọ jọ mẹrin ti Ọlọla na ṣe lọ si Orilẹ ede na.

Ọlọla Atohengbe ni Minisita Alamojuto eto iṣẹ awọn Awogbo fun Ijọba Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria, on na ni nwọn si si di adulaga Igbimọ ẹgbẹ Ifẹ ọrẹ ni ari Orilẹ ede Naijiria ati Czechoslovakia wipe si irẹpọ ti o ti wa larin awọn Orilẹ ede meje ju lọ fun ma-a gbooro siwa ju so.

Irohin fi ye wa wipe, Ijọba ti o fun Ọlọla Atohẹngbe ni anfani ẹbun na lati lọ si ilu Prague lati gba itọju ati fun igba diẹ. Ki o to tun pada wa si ile eyin o pade de ni ọjọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun osu yi.

Nigbati Ọlọla Atohengbe pada de si ile Naijiria ni ana, o sọ fun wọn Oniwe Irohin wipe, on gbadun gbogbo asiko ti on lo ninu ilu na, at pe, o jẹ ohun iyalẹnu fun on lati rii wipe awọn enia orile e d e Czechoslvaki je eniti o ni ife si awọn ọmọ Orilẹ ede Naijiria lọpọlọpọ ti nwọn si nba awọn ọmọ Naijiria ti nwọn wa ni Orile e d e na gẹgẹbi igbati o je wipe ọmọ Iya kanna gbogbo wọn.

Otun sọ pẹlu ninu ọrọ rẹ fun awọn oniwe Irohin ti nwọn wa pade rẹ lojo nape on ti koto lero pe awọn enia Orile ede Naijiria ni kan ni nwọn ni ifẹ inu rere si gbogbo enia ati p pajulọ awọn ajoji.

Otun sọ pe ifẹ inu rere ti awọn enia Orilẹ ede na si awọn ọmọ Orilẹ ede Naijiria iyanu ni.

Otu ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pẹlu pe nigbati on ti de Orilẹede ni gbogbo awọn alaṣẹ ijọba ti bẹrẹsi wa si ọdọ on ti nwọn di ntoju on lati ojọ ti on ti de inu ilu na titi on si pada de ni oni.

"Lọpọlọpọ awọn ile iṣẹ ni nwọn mu mi lo ti mọ si de gbogoo ibiti awọn enia inu ilu na ti nṣe awọn ẹrọ ti nwọn fi nṣe irin iṣẹ mọto ti ile iṣẹ ti nwọn ti nṣe mọto kan ti nwọn npe oruko arẹni "SKODA"

Ọlọla Atohengbe tun sẹ fun awọn Oniwe Irohin pe nigbati mo ti de ile pada de ile yi on yio sa gbogbo agba ti o ba wa ni ikwo mi ki olo le jẹ pe Irẹpọ ti o wa larin awọn Orilẹ ede Naijiria ati Orilẹ ede Czechoslvakia le e eyiti yio tu bọ fiidi mulẹ gbo ingboni ju ti atẹhin wa papajulọ la rin awọn enia Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria ati Orilẹ ede Czechoslovakia.

Nigbayi ni agbọṣẹpọ ti o wa larin awọn Orilẹ ede mejeji yio le ju ti atẹhin wa lọ papa larin iṣẹ Aje ati owo




AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Mase fi aye silẹ fun ... oni ṣugbọn bi o ba ri wipe are na wọra, ki o ṣe ... ki o sun fi ara lelẹ

PISCES (Feb 21 Mar 20) Ire owo, ko jina si ọ loni ṣugbọn ki o jẹki ẹnu rẹ ma bo, ko nṣe gbogbo ọrọ ni ... jade ki o ma ba sọ syiti yio yọ ọ lẹnu

ARIES (Mar 21 April 20) Tọju iṣẹ rẹ loni ki o si mo ..., ki o si mura lati gba alejo ti o mbọ wa ba ọ.

TAURUS (April 21 May 20) Eepa kan ti o ba ọmọ ... ki o si tọju asọ rẹ lati gba iyawo ... ki o dupẹ lọwọ ẹniti o lọ ba sọ ọrọ

GEMINI (May 21 June 21) Ṣe ẹjẹ loni, ... ki o se suru. Pẹlu ohun ti o wa lọwọ ni sise

CANCER (June 22 July 22) Ọjọ oni lo dasa lati fi ... soro ti o wa fun ọ mase tun fi digba m ran mọ ... wi o tun le da ija silẹ mọ

LEO (July 24 Aug 22) Ọjọ ... ni ọjọ oni nitori pe ... patakı y o ba ọ damọ an iwọ yio ...

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Gẹgẹbi ... oni ti yi ... yio mu o ki o si ranti pe loni o ni ... patakı kan, sugbon alafia ni fun o

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Ori rẹ si ngbona nitori pe ... fun o lati ... ju sugbon ... lati yanju awon isoro na

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Ire jaburate ... wa fun ọ loni ... iwọ yio ma ni ilọsiwaju si

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Tọju ara rẹ ... alafia ati itọju o si tun fẹ isinmi darada ...

CAPRICORN Dec 22 - Jan 21 Iwọ yio lori ire gba loni ... gbogbo ti o ba si dawọle loni yio yọri si rere


## Ha! Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ. A ri o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun.

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu ... ọ

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

*DISTRIBUTORS*

**Amos GBENLE & BROTHERS**
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street. West
LAGOS

# Asobade Ori-re Are Boolu

## English League

### Div 1

Arsenal v West Ham
Burnley v Aston Villa
Chelsea v Sunderland
Everton v Leeds
Man'ster U v Sheffield U
Newcastle v Le'cester
North'pton v Tottenham
Nottm F v Blackpool
Sheffield W v Fulham
Stoke v Liverpool
West Brom v Blackburn

### Div 11

Birmingham v Coventry
Bolton v Man'ster
Chalton v Norwich
Crystal P. v South'pton
Hud'sfield v Derby
Ipswich v Bristol C
Leyton O v Carlisle
Plymouth v Wolves
Portsmouth v Rotherham
Preston v Bury

### Div 111

Bournemouth v Brighton
Brentford v Exeter
Bristol R v Peterboro
Grimsby v Reading
Oxford v Gillingham
Shrewsbury v Hull
Southend v Q. P. R.
Swansea v Oldham
Swindon v Mansfield
Walsall Watford

### Div 1V

Aldershot v Colchester
Barrow v Chester
Bradford v Barnsley
Chesfield v Darlington
Hartlepools v Halifax
Luton v Notts Co.
Rochdale v Lincoln
Southport v Crewe
Torquay v Stockport
Wrexham v Bradford C

## Scottish League

### Div 1

Aberdeen v Falkirk
Celtic v Hamilton
Dundee v St J'stone
Dun'mline v Clyde
Hearts v Morton
Motherwell v Dundee U
Rangers v Kilmarnock
St Mirren v Partick
Stirling v Hibernian

### Div 11

Albion v Dumbarton
Arbroath v Stranraer
Ayr v Alloa
East Fife v Brechin
East Stirling v T Lanark
Montrose v Raith
Q of South v Forfar
Queen's Park v Berwick
Sten'semuir v Cow'beath


## APIAS RHUMATIC & DRAGES

Jẹojulowo h unhanun egbogi Jamani to lagbara gidi gidi fun iwosan LAKUREGBE" to nba enia ja



Orişirişi lakuregbe ni o wa lakuregbe Arungun ti o ma asan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbẹ orikerike danwo kori bi o ti rorun lati lo tabi ki o ma şe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi abi egusi ara wiwo, ako-iba abi pipon tabi rirun.
Bi enia ko ba gbajumo la poju rẹ lasiko o le so owo ra enia

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ATI NI SOBU
ŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN


# SURU LERE (Apa Kini)

Lati Oju Ewe keji



## Omo -- Oba Adakẹdajo

Ohun gbogbo ni akoko wa fun Adakẹdajọ ko ri jẹki Eşu fi akoko wa şofo Orun rẹ yara pari işe ọjọ rẹ lẹsẹkẹsẹ ojo titun bẹrẹsi ni ... Aşọ kan şoşo ni mo mu lọ si ori Oke, ọkan ba Olu wa rin mo wọ inu Emi mo si bere ẹsẹ mi lọwọ Oluwa şugbon mo gbo ohun na la ti inu Emi wa ti o nso bayi pe; Ẹşẹ wo ni Josẹph şẹ ki o to sọ sinu Kanga

Nigbana ni mo gbo ohun na pe ki oro Adakẹdajo ba le şẹ ni a şe nse işẹ wọnyi si wa lara Lẹhinna ni mo tun gbo ohun miran ti o nso bayi be, Baba wan ni opolopo oro o si bi omo mẹta omo kini njẹ Surulere omo keji njẹ Ẹbun Oluwa ko şe ko eyi ikẹta njẹ Fijagba

Nigbati baba won dagba ọ şe eto ohun gbogbo ti o ni o si pin gbogbo rẹ si ona mẹta o si kilo pe ti on ba ku ohungbogbo ti on pin wonyi ki ẹ jogun rẹ fun awọn omo mẹta ni tẹlẹtẹle

Ohunti nwọn kọkọ pin fun wọn ni Eni mẹta ti baba won ni, ẹgbọn gba eyi akọkọ ẹkeji gba eyiti o tẹle aburo si gba eru ẹkẹta eyi ti aburo si fi faraya pe on ko le gba ati pe iya ni nwọn fi jẹ on Aburo si tun sọ pe eleyi ni yio jẹ ohun kini ti awọn yio pin ninu nkan baba wọn.

Eyi ti işe ẹgbọn ni ki aburo wa gba eyiti on kọ-kọ mu ki o mu tirẹ wa. Şu rulere tun şe alaye pe lẹhin ọdun kan ni nwọn yio pin awọn ohun baba wọn to ku

Nigbati o şe iyawo wọn bẹrẹ nibi rọ nigbati o kan iyawo abikẹhin o fi tirẹ bi Abuke Ẹnyin Onkawe mi iyawo şe kọ silẹ, şugbọn ko le şe kọ silẹ.

O digba diẹ na ẹ o ma ka apa keji ọrọ mi ninu we Irohin Imọlẹ laipẹ yi.

# E Ma a Polowo Ọja Nyin Sinu Irohin Imọlẹ

# IROHIN IMOLE

MOLE ORE AIYE IENI GBOGBO LAWA
No 1,564 SATURDAY NOVEMBER 20, 1965 (2)

# Fix Odds Naps

Charlton v Norwich
Plymouth v Wolves
Preston v Bury
Bank on it
By:-
Prince Rankatola

Notts For v Blackpoll XBk
Preston v Bury
Stoke v Liverpool XBk

Walsall v Watford XBk
Stirling A v Hibernian
By:-
Junior Allen

Nott For v Blackpool
Walsall v Watford
Torquay v Stockport
By:-
Senior Allen

LATI OJU EWE KINI
Iwo Orun eyiti Igbimo Oluwadi Coker se eto iwadi lasiko na.

Omo egbe Demo na tun se alaye pe awon egbe Alakuko lo se eto bi nwon yio tise yan awon Agbejoro ti yio gbenuso fun awon Igbimo Oluwadi Coker eyi ti awon Agbejoro si duro lati gbenuso lasiko ti nwon fi se iwadi si awon Ile ise Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria.

O tun so ninu oro re pe ki Oloye Adeniran Ogunsanya lo se iranti re lasiko ti eto ofin pajawiri wa ni Ipinle Iwo Orun Naijiria o ni awon minista egbe Alakuko lo se eto bi awon yio se jeki Ipinle Agbede meji Iwo Orun kuro lara Ipinle Iwo Orun Naijiria.

Ogbeni Akinyele tun se alaye pe egbe Alakuko lo se ona bi Olori egbe Afenifere Oloye Obafemi Awolowo se wa nibiti o wa nisisiyi, eyiti o fi je wipe awon egbe na lo se ona bi nwon yio ti se la ti Oloye Awolowo mole titi di asiko ti nwon fi de ogba ewon bayi.

O tun se alaye siwaju si i pe egbe Alakuko ni o gbimo lati pa egbe Afenifere run eyiti o je wipe egbe na lo jeki gbogbo ohunti o nsele ni Ipinle yi ma sele.

Ogbeni Akinyele tun se alaye pe egbe Alakuko lo hu iwa Odale si egbe Afenifere ninu odun 1959 nigbati egbe Afenifere lo ba egbe Alakuko lati jijo se eto akoso Ijoba apapo Naijiria eyiti o je wipe egbe Alakuko ko si gba eto ba egbe Afenifere se lati akoso Ijoba nigbana.

O tun se alaye siwaju si i pe fun odidi odun mokanla ni o je wipe egbe Alakuko ti wa gegebi ota si egbe Afenifere ti egbe na ko si ni ife kankan si egbe Afenifere.

Ni ipari oro re, Ogbeni Gilbert Akinyele wa kesi gbogbo awon omo ile Yoruba nile ati lokun lati ni isowopo pelu ara won lati le ja fun bi Ipinle Iwo Orun yio tise dara,

Ogbeni Akinyele tun se alaye pe ki egbe Afenifere ati Demo gbagbe ohunti o ti sele lati ehin wa ki won jijo papo lati ma se eto akoso Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria,

LATI OJU EWE KINI
Awon ogbeni na tun se alaye ninu iwe ti nwon ko si Oloye Adetokunbo Ademola pe o si je okan ninu awon Igbimo ti nwon so wipe nwon fe pari edeaiyede to be sile ninu odun 1962 eyiti gbogbo ohunti awon Igbimo na lasiko so wipe nwon yio fe lati pari ija na si ja si ofo ati pe ti gbogbo na si tun fa rogbodiyan lowo ni asiko na.

Awon Akeko egbe Afenifere na tun se alaye pe yio je ohunti yio dara bi o ba le fi oju inu wo ohunti o nsele wa ki o to ase nwon bere eto lati pari ija na ba le se dabi ti odun 1962.

Awon akeko na tun se alaye pe ohunti o to ki Oloye Ademola se lori ona bi nwon le se gba pari edeaiyede to nsele ni Ipinle na ni pe ki nwon se eto na ni ona ti yio fi je wipe lori eto eto oro iselu ni nwon yio se gbe pari ija na eyiti yio je wipe awon omo egbe oselu ni Ipinle na ni nwon yio pe lati se eto bi edeaiyede na yi so pari.

Ninu ohunti o se koji ti awon Akeko na tun soro le lori ni pe eto lori bi nwon yio se da Oloye Awolowo sile si je ohunti o se pataki pupo ti nwon ni lati jiroro le lori nibiti awon Igbimo na yio ti pari ija na.

Ohunti o je iloara ti awon Akeko egbe Afenifere ti ile eko giga ti Unifasiti ilu Ibadan na ni nwon ti tun pe akiyesi Oloye Ademola si eto abayori idibo si Ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria eyiti awon egbe Akeko na so wipe o si je ohunti o ti en'a loju ati pe o si tun je ohun ti ko ba oju mu rara.

Awon Akeko egbe Afenifere na tun se alaye ninu ipari oro won pe eleyi si je ohunti o se pataki ti awon si nfe lati jeki awon Igbimo ti nwon fe pari ija na tete jororo le lori lati mo ona ti nwon yio gbe eto ti won fe fi pari ro, bi edeaiyedean to nsele ni Ipinle Iwo Orun Naijiria na.

Awon Akeko na tun se alaye pe awon yio fi ara mo eto ti awon Igbimo na ba se eyiti o ba gbogbo ohunti o se pataki ti awon so sinu iwe ti nwon ko si Oloye Adetokunbo Ademola lori ohunti o nsele ni Ipinle Iwo Orun Naijiria bayi

Awon Akeko egbe Afenifere ti ile eko giga julo ti Unfasiti Ibadan na tun tenu mo oro won pe bi awon ba tile pari oro na tan, awon ni awon ki yio gbe eto abayori idibo si Ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria eyiti awon Akeko na tun soro le lori pe jibiti tabi magudaru si wa lori eto abayori bo na.

## *National Bank Of Nigeria Limited*

## Christmas Shilling Fund-December. 1965

Depositors in the Christmas Shilling Fund are hereby reminded that in accordance with regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday 6th December, 1965.

Withdrawals can only be made by the depositor in person and on production of his/her Passbook. In the case of distant depositors, early applications for withdrawal forms should be made to the Manager of the Branch concerned: such applications to be accompanied by the depositors' Passbooks, for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on Friday the 31st December, 1965, and depositors who fails to withdraw on that day cannot do so until next Christmas.

Payments shall be made in the following alphabetical order of the depositors' surnames on the dates shown hereunder and the Contributors who fail to apply on the prescribed dates shall not be attended to until Monday, 13th December, 1965.

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | A | Monday | 6th | December, | 1965 |
| B | to | H | Tuesday | 7th | ,, | ,, |
| I | to | N | Wednesdy | 8th | ,, | ,, |
| | | O | Thursday | 9th | ,, | ,, |
| P | to | Z | Friday | 10th | ,, | ,, |
| A | & | Q | Saturday | 11th | ,, | ,, |

For the year 1966, deposits will be taken as from Monday, 3rd January, 1966.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER.

*(advertisement above)*

Printed & Published by Mokupe Printing Press 16, Bamgboye Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45' Campbell Street Lagos. 20/11/65